# Mo wa pẹlu Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ni o wa lọ sibi akitan ijọ kan, ti o si tọ ni iduro,

Lati ọdọ Hudhayfah - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Mo wa pẹlu Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ni o wa lọ sibi akitan ijọ kan, ti o si tọ ni iduro, ni mo ba takete si i, o wa sọ pe: «Sunmọ ibi» ni mo ba sunmọ titi mo fi duro si ibi ẹyin gigirisẹ rẹ mejeeji, nigba naa ni o ṣe aluwala ti o si fi ọwọ pa ibọsẹ alawọ rẹ mejeeji.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Hudhayfah ọmọ Al-yamān - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- n royin pe oun wa pẹlu Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a-, ni o wa gbero - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - lati tọ, ti o si wọ subāta ijọ kan; oun naa ni aaye ti wọn maa n da idọti ati iyẹpẹ ti wọn ba gba jade ni inu ile si, nigba naa ni o wa tọ ni iduro, èyí tí o si pọ ninu ìṣesí rẹ ni ki o tọ ni ijokoo. Ni Hudhayfah wa takete si i, ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa sọ fun un pe: Sunmọ ibi, ti Hudhayfah si sunmọ ọn titi ti o fi duro si ẹyin rẹ nibi gigisẹ rẹ mejeeji; ki o le wa gẹgẹ bii gaga fun un ki wọn ma baa ri i ni ìṣesí yẹn. Lẹyin naa ni o wa ṣe aluwala - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a -, nigba ti o de ibi fifọ ẹsẹ mejeeji, o fi mọ lórí pipa ibọsẹ alawọ rẹ mejeeji - awọn ni awọ fẹlẹfẹlẹ tabi nkan ti o jọ ọ ti wọn maa n bọ si ẹsẹ ti yio si bo koko ẹsẹ mejeeji - ti ko si bọ wọn silẹ.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee